**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**DÍDÒJÚKỌ ÌRÚNÚ ÀWỌN Ẹ̀MÍ JẸRAN-JẸRAN ÀTI MÙJẸ̀-MÙJẸ̀ (2)**
**OṢÙ KỌKANLA 2021**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 27
Ìjẹ́wọ́: Ìsáíàh 49:26

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹ̀yin gbẹ́nà-gbẹ́nà ọ̀run, ẹ dìde, ẹ fọ́ ìwo àwọn ìkà tí wọ́n yàn láti tú ayànmọ́ orílẹ̀-èdè yìí ká, ní orúkọ Jésù.
6. Ẹ̀yin ọdẹ àti pẹja-pẹja ọ̀run, ẹ fà jáde gbogbo agbára tó n gbìyànjú láti fi ẹ̀jẹ̀ bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù
7. Olúwa, jẹ́ kí àjọ àwọn jẹran-jẹran àti mujẹ̀-mùjẹ̀ lórílẹ̀-èdè yìí dahoro, ní orúkọ Jésù
8. Ẹ̀yin jẹran-jẹran àti mujẹ̀-mùjẹ̀, ẹ sígun lòdì sí ara yín, kí ẹ sì para yín run, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí ìwà ìkà àwọn ìkà tí wọ́n ṣètò láti yọ ayé mi lẹ́nu, dópin, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo gbólóhùn àti ikéde, tó lòdì sí àláfíà mi, túká, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ètò òkùnkùn fún èmi àti ìdílé mi, túká, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ètò ẹ̀rùjẹjẹ tí wọ́n mọ lòdì sí ayé mi, yọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti ba ayànmọ́ mi jẹ́, òpin dé bá ọ, kú, ní orúkọ Jésù.
14. Mo dàrú, mo sì fagilé gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ òdì tí wọ́n sọ lòdì sími, ní orúkọ Jésù.

15. Gbogbo ilẹkùn ìgbà láíláí, tó ti n dènà ètò Ọlọ́run fún ayé mi, ṣí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
16. Mo ba gbogbo ifìmọ̀ sọ̀kan, tí wọ́n ṣe lájọ àjẹ́ àti ní gbogbo gbàgede sàtánì tó lòdì sí mi jẹ́, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo adìtú ìkọ̀kọ̀, àwọn ìwé ìkọ orúkọ sílẹ̀ ibi àti gbogbo ilé ìkó ìwé pamọ́ sí ọ̀tá nílù tí a ti bími, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.
18. Ọlọ́run, dìde, sọ gbogbo ìmọ̀ àwọn aninilára mi di òfo, ní orúkọ Jésù.
19. Ọlọ́run, dìde, bú ramúramù, kí O sì borí àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
20. Olúwa, jẹ́ kí ìkórajọpọ̀ àwọn ọ̀ta lòdì símì di ìgbárajọ fuń ìdájọ́, ní orúkọ Jésù.
21. Ọlọ́run, dìde, so gbogbo Hámánì tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi rọ̀, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo òkúta ìdíwọ́ tó n dènà ètò àsọtẹ́lẹ̀ Ọlọ́run fún ayé mi, gba ifàtu, ní orúkọ Jésù.
23. Gbogbo ọ̀rọ̀ òdì tí àwọn enìyàn búbúrú ti sọ lòdì sí ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
24. Mo múso gbogbo ejò aìlera tó n yọ àgọ́ ara mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo aìlera apanirun, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, kú, ní orúkọ Jésù.
26. Mo gé dànù gbogbo ẹ̀ka àrùn àtinúwá tó n tàn kákìri ara mi, ní orúkọ Jésù.
27. Amú ìlera so, gba ìmúso nípa iná, ní orúkọ Jésù.
28. Ogun àwọn ẹni búburú àti alágbára tó lòdì sí ìléra mi, dópin, ní orúkọ Jésù.
29. Olúwa, jẹ́ kí àwọn ẹ̀yà ara mi gbóná jù fún arùnkàrùn láti gbámú, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo jẹran-jẹran tí wọ́n yàn lòdì símì, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
31. Ẹran ara mi, ẹ̀jẹ̀ mi, kọ ohùn ikú, ní orúkọ Jésù.
32. Agbárakágbára tó n jẹ ẹran ara mi, jáde wa, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
33. Agbárakágbára tí wọ́n yàn láti fimí jẹ tán, kú, ní orúkọ Jésù.
34. Mo sọ gbogbo pẹpẹ onípa di aláílàgbàrá, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo pẹpẹ ibi tí wọ́n gbé dìde lòdì símì, gba ìtíju, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo alúfà ibi, tó n ṣiṣẹ́ ìránṣẹ́ lòdì símì lórí pẹpẹ ibi, gba idà Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo iṣàbẹ̀wò tí sàtáni lórí ayé mi, di asán, ní orúkọ Jésù.
38. Olúwa, jẹ́ kí agbára Ọlọ́run dẹ́rùbá, ki ó sì mú ijákulẹ̀ bá gbogbo aláfọ̀ṣẹ tí wọ́n yàn lòdì símì, ní orúkọ Jésù.

39. Bàbá, jẹ́ kí àwọn aláfọ̀ṣẹ, àwọn babáláwo, àwọn onífáyà tí wọ́n ṣètò lòdì sími di gígé dànù, ní orúkọ Jésù.
40. Mo pàṣẹ kí àwọn iràwọ̀ nínú ipá wọn láti ba gbogbo aléni-má-dẹ́yìn olóríkúnkun mi jà, ní orúkọ Jésù.